# ÀGỌ́ TI A PA NI AGINJU

## Ẹksodu 25:8; 26:1-37; 27:9-21; 40:1-38

## ẸKỌ 70 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Awa ni irú Olori Alufa bẹ̃, ti o joko li ọwọ́ ọtún itẹ́ ọla nla ninu awọn ọrun: Iranṣẹ ibi mimọ́, ati ti agọ́ tõtọ, ti Oluwa pa, kì iṣe enia" (Heberu 8:1, 2).**

**I Awọn Itọni Ọlọrun ati Eto nipa Kikọ Agọ Naa**

1. Niwọn bi o ti jẹ pe ki Ọlọrun le maa gbé laaarin awọn Ọmọ Israẹli ni a ṣe kọ́ Agọ naa, o ṣe pataki pe ki wọn tẹle itọni Ọlọrun finnifinni, Ẹksodu 25:8, 9; Iṣe Awọn Apọsteli 7:44, 45; Heberu 8:1, 2, 5; 9:20-26
2. Ibori kin-in-ni ti inu, ninu ibori mẹrin fun Agọ naa yoo jẹ́ aṣọ ọ̀gbọ olokùn wiwẹ ti a fi iṣẹ ọnà ya kerubu si lara, Ẹksodu 26:1-6
3. Ibori keji ni a o fi irun ewurẹ ṣe, wọn yoo si ṣẹ́ bo ibori kin-in-ni, Ẹksodu 26:7-13
4. Ibori kẹta ati kẹrin yoo jẹ awọ agbo ti a fi aro pupa rẹ, ati awọ seali, Ẹksodu 26:14
5. Apako igi ti a fi wura bò ni yoo gbe ibori mẹrẹẹrin ró, pẹlu ihò-itẹbọ fadaka ni isalẹ, a o si fi igi pẹlẹbẹ pẹlẹbẹ ti a fi wura bò so ó pọ̀ ni isalẹ, a o ti wọn bọ awọn oruka wura, Ẹksodu 26:15-30; 30:12-16; 38:25-28
6. Aṣọ-ikele ti yoo pin Agọ naa si meji ni a o fi aṣọ ọgbọ ti o dara ju lọ ṣe, a o si fi iṣẹ ọ̀na ya awọn kerubu si i lara, Ẹksodu 26:31-35; Matteu 27:51; Heberu 10:19, 20
7. Aṣọ-tita fun ẹnu-ọna Agọ naa gbọdọ jẹ aṣọ ọgbọ pẹlu, eyi ti a ni lati fi abẹ́rẹ ṣiṣẹ ọna si lara, Ẹksodu 26:36, 37
8. A o ta aṣọ ọ̀gbọ yi agbala Agọ naa ká; awọn òpó rẹ̀ yoo si jẹ idẹ ti a fi ọpa fadaka so pọ̀, ẹnu ọna agbala naa ni a o ta aṣọ ọgbọ si ti o ni oriṣiriṣi àwọ̀ ti a si fi abẹrẹ ṣiṣẹ ọna si lara, Ẹksodu 27:9-19

**II Gbigbe Agọ Ró ati Tito Awọn Ọṣọ inu Rẹ̀**

9. Apoti ẹri yoo wà ni Ibi Mimọ́ Julọ lẹyin aṣọ ikele, Ẹksodu 40:1-3, 17-21; Heberu 9:3-10
10. Tabili, ọpa fitila, ati pẹpẹ wura, ni a o fi si Ibi Mimọ́, Ẹksodu 40:4, 5, 21-28; 27:20, 21; Lefitiku 24:1-9; Heberu 9: 1, 2
11. Pẹpẹ idẹ ati agbada omi yoo wà ninu agbala niwaju ẹnu ọna Agọ-ajọ, Ẹksodu 40:6-8, 29-33
12. Agọ-ajọ naa ati awọn ohun elo rẹ̀ ni a o ta ororo si lara ti a o si yà wọn si mimọ́ fun lilo ni mimọ́, Ẹksodu 40:9-12; Heberu 9:19-23
13. A o wẹ awọn alufaa, a o ta ororo si wọn lori, a o si yà wọn si mimọ́ fun iṣẹ wọn, Ẹksodu 40:12-16
14. Ogo Ọlọrun kun inu Agọ naa gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣeleri, Ẹksodu 40:34, 35; 25:21, 22
15. Ọwọ̀n awọsanma ni ọsan ati ọwọn ina ni oru ni o ṣe amọna awọn Ọmọ Israẹli ni gbogbo ọdun ti wọn lò ni aginju, Ẹksodu 40:36-38; Numeri 9:15-23; Isaiah 4:5, 6

## ALAYE

### Eredi Agọ

Ṣaaju ki awọn Ọmọ Israẹli to de ilẹ ileri wọn, nigba ti wọn ṣi n rin kiri ninu aginju, ni Ọlọrun ti n fẹ ni ibujoko tabi ibugbe laaarin wọn. O n fẹ ni ibi kan lati maa tẹ́ tabili rẹ̀ si, ibi ti atupa Rẹ̀ yoo maa jò nigba gbogbo ati ibi ti awọn alufaa -- awọn iranṣẹ Rẹ̀ -- yoo maa wà nigba gbogbo. Nipa nnkan wọnyii, O fẹ maa sun mọ awọn eniyan Rẹ̀, ki O le maa kọ́ wọn, ki O maa tọ́ wọn, ki O si le maa daabo bo wọn. Ipinnu ati èrò Rẹ̀ ni pe ki wọn le sin Oun ni ọna ti o dara ju ti atẹyinwa lọ, ati nipa isin bayii ki wọn le jẹ iṣẹ ti O ti yàn wọn fun gẹgẹ bi orilẹ-ède; pe ki awọn ti "a fi ọ̀rọ Ọlọrun le lọwọ" le jẹ ohun-elo nipa eyi ti ifẹ pipe Ọlọrun, ofin Rẹ̀ ati ifẹ Rẹ̀ fi le di mimọ̀ fun gbogbo araye.

Lati mu eyi ṣẹ, Ọlọrun fun Mose iranṣẹ Rẹ̀ ni awọn ofin ati awọn ilana kan fun itọni wọn. Ninu nnkan wọnyii ni eto isin ti ode ara wà, eyi ti yoo tọka si wiwá sinu ayé Iṣura ti o ṣe iyebiye ju lọ ni Ọrun, Ẹni ti yoo sanwo irapada eniyan, ti yoo si mú ododo Ọlọrun ṣẹ. Eto naa tobi to bẹẹ ti a fi ni lati maa tọ́ awọn eniyan naa ni ṣisẹ-n-tẹ̀lé titi giga ati jijin ifẹ Ọlọrun yoo fi di mimọ̀ fun araye. Iṣisẹ kan ninu eto nlá nlà yii ni kikọ́ ibi ijọsin yii, tabi ibugbe Ọlọrun, eyi ti yoo tán aini awọn eniyan Israẹli, nipa ti ẹmi, fun akoko naa.

### Ibugbe Ọlọrun

Nitori naa, Agọ, bi ibugbe Ọlọrun laaarin awọn eniyan Rẹ̀ jẹ apẹẹrẹ ifarahan Rẹ̀ laaarin awọn eniyan, nibẹ ni a si le ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ wọn. O jẹ ọna kan ti wọn le gbà de iwaju Ọlọrun. Ṣugbọn o tilẹ niye lori ju bẹẹ lọ. O jẹ apẹẹrẹ tabi aworan iriri mẹta ti Onigbagbọ -- igbala, isọdimimọ́, ati fifi Ẹmi Mimọ́ ati ina wọ ni – ti Ọlọrun ti ṣeleri ti O si ti pese silẹ fun awọn ti wọn ba n ṣafẹri ẹbun Rẹ̀ ti o dara ju lọ. Nipa bayii, o jẹ ojiji Kristi, Ẹni ti O gbé laaarin awọn eniyan, ati irubọ nla ti Oun yoo ṣe, ati oye Onilaja ti Oun yoo jẹ lẹyin ti O ba ti sanwo irapada wa tán. Gẹgẹ bi Agọ

ti jẹ apẹẹrẹ “awọn ohun rere ti mbọ̀,” bẹẹ naa ni awọn alufaa ti n ṣiṣẹ nibẹ jẹ apẹẹrẹ Jesu Kristi, Olori Alufaa Nla; awọn eto isin paapaa jẹ apẹẹrẹ oniruuru ọna ti Ọlọrun n gba ba awọn eniyan Rẹ̀ pade ni akoko Oore-ọfẹ yii.

Agọ naa fi apa meji Otitọ hàn fun Israẹli – ati fun awa naa: bi Ọlọrun ṣe n sun mọ eniyan ati ọna itẹwọgba ti eniyan fi le sun mọ Ọlọrun. Ni igba Ofin, ọna ti eniyan gba fi n wa oju Ọlọrun ni nipa awọn ohun ijọsin ti a foju ri ninu Agọ, nipasẹ awọn eniyan diẹ. Awọn eniyan wọnyii ni awọn Olori Alufaa, iru awọn ọmọ Aarọni. Ṣugbọn ni Igba Oore-ọfẹ, olukuluku eniyan ni o le sun mọ Ọlọrun, nipa ọna titun ati aaye – eyi ni ni Ẹjẹ Jesu – ki o si ri àlékún ibukun ati iranwọ gbà ju eyi ti ẹnikẹni le ri labẹ Majẹmu Laelae.

Kò si ọna ti a le gbà lọ si Ibi Mimọ́ ninu Agọ lai gba agbalá kọja nibi ti pẹpẹ ẹbọ sisun gbe wà, nibi ti a gbe n dari irekọja jì ti a si n mú ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ kuro. Bẹẹ ni kò si si ọna rara ti a le gba de Ibi Mimọ́ Julọ lai kọkọ gba ibi pẹpẹ wura ti o wà ni Ibi Mimọ́ nibi ti a gbe n ṣe iwẹnumọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ abinibi ati idibajẹ ọkan. A le ri nigba naa pe, a ko le sọ ẹnikẹni di mimọ́ lai jẹ pe a ti kọkọ da a lare ná; ko si si ẹni ti o le ri agbara Ẹmi Mimọ́ gba lai jẹ pe o ti kọkọ ri isọdimimọ́.

**Eto nipa Kikọ́ Agọ Naa**

Bi a ba fara balẹ ṣiro awọn ohun ti a kọ silẹ pe o ṣẹlẹ lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti (Ẹksodu 12:2; 13:4; 19:1; 20:18; 34:28) a o ri i pe a bẹ̀rẹ kikọ Agọ naa ni nnkan bi oṣu mẹfa lẹyin ti Israẹli fi Egipti silẹ. Niwọn bi eyi si ti jẹ otitọ, oṣu mẹfa ni wọn fi kọ́ ọ. Tọkantọkan ni awọn eniyan fi mu awọn ohun elo ikọle naa wá (Ẹksodu 25:1-8; 35:4, 21-29; 30:12-16) a si ri i ka pe wọn fi itara gidigidi hàn si iṣẹ naa: wọn tilẹ mu wá ju bi a ti beere lọ. A ṣiro iye ti o pari Agọ naa si nnkan bi ọkẹ marundinlọgọrin dọla ($1,500,000 -- eyi si jẹ ọpọlọpọ ọkẹ naira ni iye owo ti wa ti ode oni).

A o ri ninu ẹkọ wa pe ipa pupọ ni ile naa pin si, ipa kọọkan ni o si yanju gedegbe. Ekinni ni gbọngan gbọọrọ ti a fi patako kọ́ ti a si gbero sori awọn ipilẹ fadaka ti o ni ihò-itẹbọ ninu, a si fi awọn ọpa idabu igi ti o gba inu oruka wura kọja so wọn pọ̀. Gbogbo igi patako ati ọ̀pa-idábu naa ni a fi wura didara bò.

O ni iye aṣọ-tita ti a fi bò gbọngan yii. Ekinni ni aṣọ Agọ́ ti a ṣe ni aṣọ-tita mẹwaa; ti aṣọ-alaro, ati elese-aluko, ododó ati ọgbọ olokun wiwẹ ti a so pọ mọ ara wọn. Eyi to iwọn ti yoo bo oke, ẹyin ati ẹgbẹ meji, ti afo ti yoo wa nisalẹ ko si ni ju igbọnwọ kan lọ silẹ. A fi iṣẹ ọna ya awọn kerubu sara aṣọ wọnni.

Loke aṣọ Agọ, ibori ti a tun ṣe jẹ aṣọ tita irun ewurẹ. Eyi tobi ju aṣọ Agọ lọ, nitori aṣọ-tita mọkanla ni a fi ṣe e dipo mẹwaa. O balẹ o si bo aṣọ-tita ti inu patapata, eyi ti a ṣiṣẹ ọna meremere si lara, ti o si jẹ pe lati inu nikan ni a ti le ri i bayii. A mu ki oju isolu ibori ti irun ewurẹ tase oju isolu ti aṣọ Agọ nipa ṣiṣẹ aṣọ-tita po niwaju Agọ, nipa bẹẹ apa kan aṣọ-tita akọkọ di iṣẹ́po meji. Eyi dí gbogbo oju isolu, ko si ṣe e ṣe fun imọlẹ, ekuru tabi omi lati wọle. Awọn ibori meji ikẹyin jẹ ti awọ àgbo ti a fi aró pupa rẹ, ati awọ seali; wọn si bo inu Agọ naa patapata to bẹẹ ti imọlẹ, ekuru tabi omi ko le wọle.

A fi aṣọ-ọgbọ kan bo iwaju Agọ naa, eyi ti o ni àwọ̀ oriṣiriṣi gẹgẹ bi ti aṣọ Agọ, a si fi àbẹrẹ ṣiṣẹ ọna si i lara gẹgẹ bi a ti fi han Mose lori Oke Sinai.

Aṣọ ikele kan wà ninu Agọ naa ti o pin in si meji, a si pe apa kan ni Ibi Mimọ́ ati apa keji ni Ibi Mimọ́ Julọ. Awọn alufaa maa n lọ si Ibi Mimọ́ fun iṣẹ-isin wọn ojoojumọ. Ọpa fitila wura nla kan tan imọlẹ si Ibi Mimọ́ naa. Olori Alufaa nikan ni o n wọ Ibi Mimọ́ Julọ, lẹẹkan lọdun si ni, ni Ọjọ Etutu. Ṣẹkina ogo Ọlọrun ni o tan imọlẹ si yàrá yii, o si jẹ eewọ lati jẹ ki imọlẹ lati ita wọ ibẹ̀.

Agbala kan wà lode Agọ naa ti a fi aṣọ ọ̀gbọ̀ olokun wiwẹ yika eyi ti o ga ni igbọnwọ marun-un. Gigun agbala naa jẹ ọgọrun-un igbọnwọ o si fẹ to aadọta igbọnwọ. Giga Agọ jẹ igbọnwọ mẹwaa, nitori naa awọn Ọmọ Israẹli le ri i loke aṣọ-tita nigba ti wọn ba n bọ̀ lati rú ẹbọ wọn tabi lati gbadura ni akoko isin ojoojumọ. Ẹnu-ọna iwaju agbala ni a fi aṣọ ọgbọ bò, eyi ti a fi abẹrẹ ṣiṣẹ ọnà si lara, ti o si ni àwọ kan naa pẹlu aṣọ ti a ta siwaju Agọ. Agbala yii jẹ apẹẹrẹ idalẹbi fun ẹ̀ṣẹ.

**Awọn Ohun-elo ati Itumọ Wọn**

Ninu agbala ni a gbe pẹpẹ ẹbọ sisun si, eyi ti a n pe ni pẹpẹ idẹ. Laaarin pẹpẹ yii ati Agọ gan an ni agbada omi wà. Niwọn bi o ti ṣe pe lori pẹpẹ ẹbọ sisun ni a ti n pa ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ ti a si n fi i rubọ, ẹni ti o ba sun mọ ọn gba pe oun jẹ ẹlẹṣẹ ti o n fẹ idariji. Nitori bẹẹ o rọrun lati ri i pe pẹpẹ idẹ naa jẹ apẹẹrẹ idalare, tabi igbala kuro ninu ẹṣẹ. Agbada omi si jẹ apẹẹrẹ iribọmi.

Fadaka ti a fi ṣe ipilẹ Agọ́ ati ọsọ ti o wà lori awọn òpó ti o gbe aṣọ-tita ti agbala ró fi hàn pe o jẹ apẹẹrẹ owó irapada wa. A gbọdọ ṣe irapada fun awọn ti o ba tọ Ọlọrun wá gẹgẹ bi olusin tootọ. A ri eyi ninu Ẹksodu 30:11-16. Eyi fi hàn pe gbogbo eniyan ni o ti sọnu, ko si iyatọ, gbogbo wọn ni wọn si n fẹ irapada. Ọlọrọ ko le san ju iye ti a n beere, eyi ni ni aabọ ṣekeli (nnkan bi kọbọ mẹẹdogbọn), awọn talaka ko si le san din ni iye kan naa. A pe e ni owo ètutu. Ninu Ihinrere gbogbo wa ni a ni iye kan naa lati san fun igbala -- iyọọda ara ati ọna wa patapata fun Ọlọrun. Ko si ojusaju fun ẹnikẹni lati san din si eyi, ko si si ẹni ti o le san ju bẹẹ lọ.

Ibi Mimọ́ n sọ ti iriri oore-ọfẹ keji ti o daju, ani Isọdimimọ́ patapata (Heberu 13:11-13). A fi ẹjẹ awọn ẹbọ kan wọ́n iwo pẹpẹ wura, lati ibi ti eefin turari ti maa n goke lọ sọdọ Ọlọrun nigba gbogbo. Turari ti a n jo nigba gbogbo yii jẹ apẹẹrẹ adura ati idapọ mimọ́ ti a dana rẹ̀ sọkan ẹni ti a sọ di mimọ́ ni tootọ, eyi ti ko si le si ninu ọkàn ẹni ti gbongbò ẹṣẹ ati imisi ti ara n gbé (Orin Dafidi 141:2). Ko si iná tabi turari ajeji ti a gbọdọ fi sori pẹpẹ wura. Bi ina naa ba n fẹ atunṣe rara a ni lati mu ẹ̀ṣẹ́-iná lati ori pẹpẹ idẹ, nibi ti ina ko gbodọ kú nigba kan nitori ọwọ́ Ọlọrun ni o tan an ni akọkọ.

Lori tabili wura ni a fi akara ifihan si, eyi ti i ṣe apẹẹrẹ ounjẹ ẹmi ti a n jẹ nipa idapọ ti a ni nigba ti a wọ Ibi Mimọ́, -- iriri Isọdimimọ́ patapata. Akara yii ki i ju, bẹẹ ni ki i dibajẹ nitori ni ọjọọjọ Isinmi ni a n paarọ rẹ̀. Eyi fi hàn wa pe a ni lati maa wá si tabili Oluwa nigba gbogbo fun ounjẹ ti ẹmi. Ibukun ti ọsẹ yii ko le to fun ọsẹ ti n bọ̀, ṣugbọn a ni lati maa gbà si i lọtun nigbakuugba. Wo bi eyi ti ṣe pataki to, paapaa ni Ọjọ Oluwa kọọkan, a maa n wá si ibi ti Ọlọrun ti ya sọtọ ti O si ti bu ọlá fun gẹgẹ bi ibugbe Ẹmi Rẹ̀, lati maa gba ounjẹ ọtun lọdọ Rẹ̀.

Ọpa fitila wura nì jẹ apẹẹrẹ imọlẹ Ọrọ Ọlọrun ati oṣuwọn Ẹmi Mimọ́ ti a fi fun olukuluku ọmọ Ijọ tootọ, ki o ba le jẹ imọlẹ fun araye (Ifihan 1:12, 20; Matteu 5:14). Iná yii ki i kú, ṣugbọn nipa ijolootọ ati aijafara lati maa boju to o lẹẹmeji lojoojumọ, a maa jo nigba gbogbo. Kiki ororo olifi ti o dara ju lọ ti o jẹ ọrẹ atinuwa awọn Ọmọ Israẹli ni a n lò fun awọn atupa ti o wà lara ọpa fitila yii.

Lẹyin naa ni a ri aṣọ ikele nlá nlà nì, eyi ti a ko gbọdọ fà si ẹgbẹ kan tabi ki a ká a soke laaarin ọdun, titi di Ọjọ Etutu. Eyi ni o pa ààlà laaarin Ibi Mimọ́ Julọ, nibi ti ogo Ọlọrun wà ati Ibi Mimọ́ nibi ti a n mu ẹjẹ wá lati fi ṣetutu fun idibajẹ araye ati ẹṣẹ abinibi. Bawo ni awọn alufaa wọnyii yoo ti kun fun ẹ̀rù mimọ́ ati ọ̀wọ̀ to bi wọn ti n de ibi aṣọ-ikele naa lojoojumọ, ti wọn si mọ̀ pe ni odi keji rẹ ni ifarahan Ọlọrun Olodumare Mimọ́ gbe gunwa ninu ọla nla Rẹ̀!

Lẹyin aṣọ ikele ni Apoti Majẹmu wà, eyi ti a fi patako ṣe ti a si fi wura bò, ninu eyi ti a si fi awọn walaa Ofin si. Ni akoko kan lẹyin naa a gbe ikoko wura ti manna wà ninu rẹ̀ ati ọpa Aarọni ti o rudi sinu Apoti-Majẹmu naa (Heberu 9:4). Wura ti o peye ni a fi ṣe ideri Apoti-Majẹmu naa, a si pe e ni Itẹ Aanu. Loke rẹ̀ ni awọn kerubu wura meji na iyẹ wọn, wọn si kọju si isalẹ lati wo Apoti Majẹmu ati awọn nnkan ti o wà ninu Rẹ̀.

Ibi Mimọ́ Julọ jẹ apẹẹrẹ iriri nla kẹta ti Onigbagbọ́ ti i ṣe ifiwọ ni Ẹmi Mimọ́, ti anfaani rẹ ṣi silẹ nigba ti aṣọ-ikele Tẹmpili faya nigba ti Kristi kú, ti a si kọ́ fi fun ni ni Yara Oke ni Ọjọ Pẹntikọsti. Nigba ti Oluwa ṣeleri Olutunu yii fun wa, O wi pe nigba ti O ba de inu ọkàn wa, yoo maa tọ́ wa si ọna otitọ gbogbo. Apoti Majẹmu naa, pẹlu awọn okuta walaa jẹ apẹẹrẹ Ọrọ Ọlọrun ninu ọkàn wa. Awọn kerubu naa jẹ apẹẹrẹ mimu ofin Ọlọrun ṣẹ; Itẹ Aanu si jẹ apẹẹrẹ Kristi bi O ti duro laaarin ododo Ọlọrun ati ofin, ati imuṣẹ rẹ̀, ki iran eniyan ma ba ṣegbe titi lae.

**Ibi Ti A Pa Agọ Naa Si**

Ni aarin ibudo awọn Ọmọ Israẹli ni a pa Agọ naa si. Ila-oorun ni ẹnu-ọna rẹ maa n kọju si nigba gbogbo. Oluwa sọ fun Mose pe ki o pa agọ ti rẹ̀ ati ti Aarọni ati ti awọn alufaa iyoku siwaju ẹnu ọna agbala. Awọn ọmọ Lefi ni lati pagọ yika agbala naa ni iha mẹta iyoku ki awọn ti a kò ya si mimọ́ má ba sun mọ ile ọ̀wọ̀ yii pupọ ju, ni akoko ti ko tọ́, ki wọn ma ba si tabuku si i. Awọn ẹya ti o ku ni yoo pagọ yika ni iha mẹrẹẹrin, ẹya mẹta ni iha kọọkan.

Nigba ti Oluwa ba fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli tẹsiwaju, awọsanma a kuro lori Agọ a si sun siwaju. Awọn alufaa a si wọ inu Agọ lọ wọn a si ko gbogbo ohun elo mimọ́, wọn a si di wọn sinu awọn oriṣiriṣi aṣọ Agọ. Nigba naa awọn ọmọ Lefi a bọ́ siwaju, ẹni kọọkan a si gbe ohun-elo ti Ọlọrun ti yàn fun un gẹgẹ bi idile rẹ̀. Nibi ti wọn ba tun de lati pagọ si, awọn ọmọ Lefi a si yara gbe Agọ́ naa kalẹ; aye ti wọn wà nigba ti wọn ba n rin lọ mu ki o rọrun fun awọn Ọmọ Israẹli lati pagọ si aye ti a ti yàn fun wọn lai si idaru-dapọ.

Nigba ti a kọkọ gbe Agọ́ naa kalẹ, ọkan irẹwẹsi awọn Ọmọ Israẹli yoo ti sọji tó, itara wọn yoo si ga si i lọpọlọpọ, odò ayọ yoo si ti ṣàn tó ninu ẹni kọọkan nigba ti wọn ri awọsanma ti o fi ọla nla sọkalẹ sori Agọ ti o wà lori ilẹ! Bayii Ọlọrun ti ni ibugbe laaarin awọn eniyan Rẹ̀; niwọn igba ti wọn si n rin ninu ibẹrù Oluwa, ogo ifarahan Oluwa si "kun inu agọ́ na" (Ẹksodu 40:34), wọn si mọ̀ pe awọn ni Amọna ti ki I kuna ati Aabo ti o daju.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi paṣẹ pe ki wọn kọ́ Agọ naa?
2. Darukọ ohun mẹrin ti a fi bo Agọ naa.
3. Ki ni pin Agọ ti inu? Iṣẹlẹ nla wo ni o ṣẹlẹ lọjọ iwaju ti o mu iyipada wa ninu ipaala yii?
4. Ki ni awọn iho-itẹbọ fadaka, tabi awọn ipilẹ wọnni duro fun? Nibo ni fadaka naa ti wá?
5. Ki ni a fi ṣe agbala naa? Bawo ni a ṣe paala rẹ kuro ni ibudo awọn Ọmọ Israẹli?
6. Awọn ohun elo wo ni o wà ninu agbala? ni Ibi Mimọ́? ni Ibi Mimọ́ Julọ?
7. Bawo ni Israẹli ṣe n mọ igba ti o yẹ lati bẹrẹ irin ajo wọn?
8. Ta ni pagọ siwaju Agọ naa? Awọn wo ni o pagọ ni iha kọọkan?
9. Bawo ni Israẹli ṣe mọ pe inu Oluwa dun si wọn, O si wà laaarin wọn?
10. Ṣe alaye nipa oniruuru iṣẹ awọn ọmọ Lefi ati ti awọn alufaa.